# EKO AKETE.

"Emi vio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. VI. No. 272 SATURDAY, APRIL 28, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



## *White's Radical Gonkiller.*

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

Victor White, Esq., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

Price: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*



NIGERIAN SECR... 2 MAY 1928



EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nje ki o ri aye wu arun mi silẹ.

"AWA O MA JO, AWA O MA YO, NI"

Aga ati Asia (Flags) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ẹgbẹ, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATOKO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

*Office* :—
No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

---

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-okọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra uy[illegible]in nibẹ.

**Are you a Mechanic ?**—If so you must want Tools, now or soon.

**Do you intend to put up a house ?**—Then you will require Builder's Hardware.

In either case you cannot do better than call at

**B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores**

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

---

**J. C. VAUGHAN**

Ti ile ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati onir[illegible] ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ [illegible] awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna : bi o le [illegible] awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati[illegible] nibẹ :

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, g[illegible] l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba ka[illegible]

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo A[illegible] Ajanaku lọjọ to ti pẹ : bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ n[illegible] kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai ! bi o ri orişirişi [illegible] ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, [illegible] Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (Saw[illegible]) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ A[illegible] re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremerejibe

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

ỌMỌDE EKO NDIDA NDI'BỌN LAI Ṣ'ỌTẸ.

Ẹnu kekere kọ lo ya ni lati gbọ pe awọn Ẹgbẹ ọdọmọdekunrin ti a npe ni Alikali di ẹgbẹ ti a gbọ pe nwọn huwa jagidijagan nisisiyi gẹgẹbi a ti gbọ iro na si.

Otitọ ha ni awọn Ọpa Ọba mu diẹ ninu wọn pẹlu nkan ọṣẹ ti a sọ pe nwọn nlo bi?

FỌṢỌFỌṢỌ ETIDO, DẸ DẸ O!

Ki awọn ti nwọn nfi aṣọ pẹpẹpẹ ṣe fifọ leti omi Ilo ṣọra nitori ki nwọn ma ba lọ fara gba lọdọ awọn "Akẹran". Ori lo yọ diẹ ninu awọn enia wọnyi ni ọsẹ to kọja nigbati nwọn tẹ fada aṣọ fifọ s'eti omi Ilo kan lọna Oke Popo: ninu eyiti a nsọ pe owo pọ nilu yi, lai sọ nkan miran ko yẹ ki awọn kan jẹ kunmoyo ati lọ gbọn owo danu sibi ti ọpa ati ti mu pada ko to lẹ.

AKỌSẸ-BỌWABA APAPANDODO.

Ni *Monday* ọsẹ yi ni a gbọ pe igi-aba kan ti a sọ pe o wa lapa eti ebute Ẹhin-gbẹti leti ile Bero lailai ya lojiji, o si ṣe obinrin kan leṣe tobẹ ti awọn Ọpa Ọba fi gbe digbadigba o di ile Alarun l'ọdan, a gbọ pe igi na ṣe leṣe tobẹ ti nwọn ko fi gbọ ẹmi lẹnu rẹ rara.

IWE OWO ASINGBA DI OMUMUYEYẸ.

Yẹyẹyẹ la nri awọn ẹniti nwọn npin iwe-iṣiro owo asingba kakiri ilu, ilu si kun fun ikan ko jọkan inira ti owo asingba yi le mu wa.

ỌNA ỌFUN ỌNA ỌRUN.

Lati bi ọjọ melo sẹhin ni a ti ri oye pe awọn onjẹ pataki meji ti ilu njẹ, gari ati agbado ti gbe owo leri, o yẹ ki a mọ ohun ti o fa sababi ọwọn awọn onjẹ mejeji na laseko yi—agbado ni ko ye loko mọ ni tabi gbaguda ni nwọn ko gbin mọ? Ko ye wa o, ẹnyin oniṣowo, nitori ọna ọfun ni ọna ọrun.

O MU YAN-YAN-YAN O MU!

Ko si bi o ti jẹ ni orun ti o bẹrẹ si ran lati ọsẹ ti o kọja, orun na mu kabari tobẹ ti o fẹrẹ le ma ta pupu ni ara enia bi igbati agbado gbugburu nta ninu agbada, nigbati orun nmu to bayi, njẹ bawo ni ojo ọdunni ti ma ri wayi? Ki Ọlọrun ṣọ wa lọwọ musiba o, aṣẹ—Amin!!

IṢẸ OPOPO VICTORIA.

A nṣe akiyesi nisisiyi pe iṣẹ ọna ti awọn Alabojuto ilu nṣe ni opopo yi ṣọ nku rebete lati de Ita Tinubu: ohun ti a fẹ gba Ijọba ni imọran nibẹ ni wipe yio dara bi nwọn ba le ṣe eto pataki nipa awọn mọto fun opopo na, bi o ti jẹ wipe, lati igbati Ijọba ti dari mọto si ọna *Broad Street* lọ si Oke Odo, a koi gbọ pe mọto tun ṣe ẹnikan ni jamba—ẹ ba wa fi oju si i.

YE PARIPA ORO BABA O......O!

Pẹkireki la ṣe alabapade ọmọdekọnrin kan ti ẹjẹ nṣe ṣoro loju rẹ ni apa adugbo kan larin ọsẹ yi. Nwọn sọ fun wa pe nigbati awọn ọmọde meji kan nle 'ra wọn kiri, ti ọwọ ko si ba ara wọn, ni eyiti o nle ekeji rẹ he oko pa pe ki on sẹ mọ eyiti o nle lo ba lọ ya bara lọ ba ọmọdekọnrin na loju, bi ko ba si wipe oju lọwọ, ọgangan ẹyin ju ni oko na iba ṣe ṣọ si, nitoriina a bẹ nyin ki ọlọmọ kilọ ẹre ọko fun ọmọ rẹ, ki omiran ma pọn ọmọ ti ẹsẹ rẹ ma wọlẹ lọ ba obi rẹ nile.

### JANMA MUSULUMI, SADAKATA.

O ta si wa leti fẹnrẹn ni lọlọyi pe awọn Musulumi nwewe lati gbe Mọṣalaṣi Jimọ ni iyawo, a si ro wipe nwọn ti fọn si iṣẹ ti tun Mọṣalaṣi "Mọka" yi ṣe nisisiyi; yio dara ni atapa ni gan 'ku, ẹni gan 'ku, ara rẹ lo gan, ọwọ a ran o!

### KASA! AGBAKO NLA!!

Gbukẹ ni a gbọ lọjọ *Tuesday* ọsẹ yi pe mọto fi obinrin kan ṣe bakaya lọkankan Busọ awọn Ọpa Ọba ni Iddo—ogun mọto ha tun de kọ un? Ọlọrun ma jẹ a rin lọjọ ebi np'ọna o.

### PẸKI LAKE NMỌ.

O ya ni lẹnu nigbati a gbọ pe ojo to rọ lowurọ ọjọ *Thursday* ọsẹ yi san ara pa enia mẹta li ebute Alakoro, o pa ọkọnrin meji ati obinrin kan, Oluwa rere gba wa l'odo l'odo lọwọ agbako, a ko mọ bi eyi ti jẹ o.

### ẸHIN IYA A DARA O.

A ba Ọgbẹni Alao Kester kẹdun iku iya rẹ ti o ṣẹlẹ ni Satide ọsẹ to kọja. A ki Ọgbẹni wa yi, Ọgbẹni T. I. Kester ati awọn ẹbi to ku, ẹ ku aṣẹhinde.

---

## IWE IPINGUN ATI BABA-NSINKU.

APA KEJI.

---

Lati ọwọ KEKERE AWO.

---

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Iṣẹ ti o mbẹ nidi ogun pinpin fun awọn ẹnit o pin ogun silẹ loju wọn ki nwọn to ku ko kere; ẹlomiran ti o ba ti ni aniyan lati fun awọn ọmọ rẹ ni ogun ma nyi iwe ogun rẹ pada lọdọdun tabi loṣu mẹfẹ-mẹfa, ẹlomiran ẹwẹ si ma nyi tirẹ pada ni oṣu mẹta-mẹta.

Nibẹ li ẹlomiran si wa ti o jẹ wipe iwe ogun ti o ba ti ṣe lẹkan ko tun ni yi pada mọ titi yio fi ku, bi o ba ti rọ olukuluku lọrun si ni.

Awọn ẹlomiran si mbẹ nigbati nwọn ba wa ninu aisan ni nwọn ma damọran lati ṣe iwe ogun.

Ohun ti a ro wipe o nmu awọn ẹlomiran nyi iwe ogun wọn pada, nigbagbogbo ni pe o wa lori wọn gẹgẹbi oye ti nwọn ba nri larin, ẹbi ọmọ, tabi ... kan.

Nigbati ẹlomiran ba wa ni idubulẹ-aisan, ọmọ miran le ṣe aibikita fun aisan baba rẹ, nipa bayi yio mu ki ẹlomiran fi ibinu rẹ yi iwe ogun rẹ pada, ọmọ miran si le ma huwa aiṣe dede pẹlu baba rẹ ri, ti baba na ba si ti pin ogun ti o yẹ ọmọ ... silẹ fun u, ti o ba si tun ri wipe o yi iwa ti o ... pada eyi le wu lori lati tun iwe ogun ṣe nipa ... ẹtọ ti ọmọ bẹ ba tun nhu—nipa bayi ni ọran ... ogun ti ṣe ni iṣẹ gan ninu fun awọn ẹniti o ba ... ṣe iwe-ogun.

Ṣugbọn ti ẹlomiran ba ṣe iwe-ogun silẹ ti ... rẹ ba si ku ti ogun na ba yapa loju ọmọ ... idi rẹ ni nwọn fi ngbe ara wọn lọ si ibi ti ... gbe dun 'lẹ lati ri wipe ogun na di okibo—... bi a ti wi ni ọsẹ to kọja.

Ti nwọn ba gbe ọran ogun na de ibi ti o ... o ba jẹ wipe ṣeria wa ninu wipe ki nwọn ... na di okibo, o le lọ bẹ ṣugbọn ti ko ba ni ... pataki kan lori, a jẹ wipe bi oluwarẹ ti ṣe ... ipingun yi bẹ gan lo jẹ

Awa ri gbangba wipe iṣẹ pataki gan lo mbẹ ... idi iwe-ipingun pataki lẹhin ti o ba to asiko ... ni lati yanri ogun si bi kan eyiyi ni asiko ... lati pin, bi iṣẹ pataki ti mbẹ nidi rẹ bi a ti wi ... bẹ lo mbẹ fun awọn ẹniti nwọn fi nṣe Baba-... ku fun ogun.

Baba-nsinku ti o ba jafara lati ba awọn ... oloku yanri ogun baba wọn sibi kan lai si ... tabi awọn ọmọ-oloku le dide lati jẹ ki Baba-nsinku bẹ ṣe akanta bi nkan wọn ti lọ si, ti o ba jẹ ... ti o le mu akiti-yan dani larin Baba-nsinku ati awọn ọmọ-oloku. nwọn le gbe si ode fun aiye ... wipe ki nwọn ba wọn da si i.

Nipa ijafara bayi o nmu ọpọlọpọ Baba-nsinku jẹbi awọn ọmọ-oloku nitorina iṣẹ ti o mbẹ ... rẹ ko kere arara awọn Baba-nsinku lo ni lati ... ṣọra nwọn ko si ni lati fi ẹhin oku-ọrun da'gu nitori ki nwọn ba lugbadi aiye.

Gẹgẹ bi iṣẹ ti o mbẹ ni idi Baba-nsinku ti ... ti o si jẹ iṣẹ wahala jojo, ẹ jẹ ki a ka ọna ti ... ni lati gba ki nwọn to le pegede ni idi rẹ.

Ekini: nwọn ni lati ṣọra gidigidi ki nwọn ... ba lugbadi duniyan.

Ekeji: nwọn ni lati ṣe otitọ awọn ko gbọdọ ... mọkaruru arara.

Ẹkẹta: nwọn ko ni lati fi ogun 'jafara, bi nwọn ba fi ogun jata ijangban ti nwọn ba kan nidi rẹ, ki iṣe laifi awọn ọmọ-oloku laifi awọn Baba-nsinku papa ni, ẹwẹ oku-ọrun papa ni lati ba wọn ... ẹjọ ni Kotu Ọlọrun, eyiyi ni ọjọ igbẹhin Alikiyamọ.

Ękęrin: nwọn ko ni lati fi ogun şe ojusaju, ti nwọn ba fi şe ojusaju, ede-aiyede ti o ba şęlę inin rę awọn tikalarawọn lo wa a.

Ọna pupọ lo wa nilę fun awọn Baba-nsiku ti nwọn ni lati şe ni işę nigbati nwọn ba ti tọwọ bọ ike pe awọn fę joye baba-nsinku.

Şugbọn loni awọn miran ninu baba-nsinku ti ogun ti nwọn ni lati bojuto tafala totọ ti o mu ki nwọn lọ yọju si ibi ti nwọn ni lati ma kololo fi nwọn si ni lati ma sọ inago tabi oyinbo agbara nwọn o si ma lagun ni igi imu pęlu bi eyiti o mu ewe oruwọ.

Di bi a ti nwi lọwọ yi ọpọlọpọ ogun lo mbę nilę fun awọn Baba-nsinku miran ti nwọn ni lati yanju, şugbọn ti nwọn ko i ti bikita lati dide si, bi a ba ti awọn ọmọ-oloku miran ti nwọ ba dide pe awọn ję mọ bi gbogbo nkan ti nlọ, ki işe laifi wọn, bi koşe laifi baba-nsinku ti o ri wipe o tọ o yę ki on yanju ęru ti on gbe ka 'ri ti ko si mura eto wọn.

Nitorina a bę gbogbo awọn Baba-nsinku ti nwọn ma nfi ogun jafara, ki wọn maşe jęki ọran wọn de ibi ti gbangba dękun ki nwọn to şęşę jigiri si ęru ti nwọn gbe kari: ọrọ pupọ la bo mọlę lati sọ, şugbon ti a ba woye titi ọjọ męta, ti a ko ba ri oye pataki, nigbana ni ao tu ifun ọni, a ko i fę tu ifun ọni nisisiyi—o nro kiki lọkan ọpọlọpọ Baba-nsinku miran, ę maşe jęki o şę lori niyn o ijafara pęlu ewu lo nrin.

Ọpọlọpọ ogun lo mbę nilę lọwọlọwọ yi ti o tọ ki ilu mọ ibiti o gbe fara ti si—ki lo fa sababi ti ilu ko fi gbọ 'kan?

## LABARI KUKURU NI MỌŞALAŞI—JIMỌ.

Ni ọjọ Jimọ ijęsan ogunjọ oşu yi, a gbọ wipe Alaji Isa ọmọ Shitta Bey dide o sọrọ kukuru kan si eti Jamat, awa si ro wipe o tọ ki fi si gbangba.

Mo gbọ wipe o ni o yę ki awọn Jamat dide ki nwọn lọ ri Ijọba nipa gbigbe ti awọn Alabojuto ilera-ilu ngbe oku lọ yęwo ęwę nipa ọran itę-oku wọn—o si sọrọ anu tobę ti a fi gbọ wipe awọn Jamat nşe sawura nisisiyi lati lọ ri Alaşę-ilu (*Administrator of the Colony*,) yala nwọn ti lọ nwọn ko i ti lọ a ko i mọ, bi o ti wu ki o ri, ti a ba gbọ wipe nwọn lọ ri i, a o jęki ę mọ bi gbogbo alamọri ọran na yio ti lọ si.

## ALAŞĘ-ILERA-ILU.

Awọn *Town Council* yan awọn Alaşę-ilera-ilu-lati ma toju-ilu ati Munisiba ati Alaşę-ilera ilu abę Ijọba ni gbogbo wọn wa Ijọba lo nran wọn lọwọ.

Awọn Alaşę-ilera-ilu işę nwọn ni lati ma nbojuto ilera ilu, ti nwọn ba nbojuto ilu lọna ti o yapa fun ilu:—ilu ni lati dori kodo ki nwọn si ri Ijọba lati pa irufę ọna bibojuto ilu bę mọlę, papa ti awọn Musulumi-ilu ba dide wipe awọn fę yi àşá miran pada, ti o ję aşa ti o lodi si ęsin, o dara pupọ lati şe aşaro gan le lori.

Awọn Musulumi nsọ nisisiyi pe o lodi si ęsin Musulumi lati ma gbe oku Musulumi lọ fun ayęwo lati ri yękini ohun ti o fa sababi iku rę.

Eyi le ję ętọ pataki fun awọn Alaşę- ilera-ilu lọna ibojuto ilera ilu—sibęsibę ọna odi lo ję fun awọn musulumi ninu ęsin wọn nitori o tabuku si ęsin wọn.

Ki işe nipa ọna yi nikan lo ję pataki tiwa, fun awọn Alaşę-ilera-ilu ni ero ọna miran tun mbę lọtọ ti nwọn le gba lati bojuto ilera-ilu, eyiti a ko le tọka si, şugbọn awọn munisiba papa ko şai mọ, o dara pupọ lati ro ero pataki nipa eyi ki awọn Alabojuto-ilera-ilu si mu gbigbe oku awọn Musulumi lọ yęwo kuro lọna yala nwọn ni Dokita nwọn ko ni Dokita ti o ntọju oku nigba aisan rę—ọrọ pataki li eyi ję fun awọn Musulumi şugbọn o di igba ti nwọn ba fa ọran na de iwaju Ijọba na ki a to mọ ohun ti a tun le sọ si.

## OKU GBIGBE-YĘWO.

Nigbati awọn munisiba dide lakọkọ ti nwọn bęręsi gbe oku lọ yęwo, nipa Ajakalę-arun.

Awọn Musulumi dide lati kọ àşá yi lọdọ Ijọba. a şe iranti pe awọn Imale miran tun dide pe awọn ko lọwọ si alamọri ọran na, nipa ai ko ęnu yi, ko ję ki awọn Munisiba le mọ ohun ti Ijọba yio şe si àşá awọn Ijọba ni pe ti ilu ba fę wipe ki Ijọba şe; ohun pataki fun wọn, nwọn a ni ki nwọn lọ ri ęnu arawọn daradara, lęhin ti ęnu ilu ba ko bayi, nigbana ni nwọn le mọ ohun ti awọn le şe le lori.

Şugbọn nigbati awọn ara ilu ba nfę atunşe pataki larin wọn lọdọ Ijọba, awọn apakan a tun ma gbęhin lọ yi ęnu wọn pada, irutę iwa yi lo nmu ki awọn ara ilę yi ma gbe nkan anfani wọn sọnu.

Ninu gbogbo Musulumi to mbę ni ilę yi loni ati Wukuwuku ati Kemberi tani ko mọ wipe kikun oku Musulumi bi Ęran-ileya ko yapa ni ọna ęsin wọn? Şugbọn munafiki ati iwa tęmbęlękun le ję ki ęnu wọn le ko lati dide si, ki nwọn si ri wipe awọn Alaşę-ilera-ilu ri si fun wọn, eyiyi ni ętọ pataki ni ilu.

Bi o tilę wu wọn lati fi ęnu ko ęnu, a ko ni şai ri, Kiriyo omiran tabi ko şe Imale ko şe Keferi ti yio ma ti nwọn ni itikuti.

Gbogbo Musulumi ę fi ọtę silę nipa eyi ki ę dide ki ę lọ ri awọn Ijọba ki nwọn ba ayin rin irin ọran yi lọdọ awọn Alaşę-ilera-ilu.

## ITĘ OKU IMALE.

Nipa ọran Itę-oku awọn Imale ti a tun gbọ wipe awọn Jamat nku le lori yi, pe o jinna fun awọn lati ma lọ sinku si Atan.

Mo şeranti pe ni ibẹrẹ ti awọn *Lagos Town Council* da imọran yi, awọn Jamat fi ọran na si iwaju Egbẹ Dẹmọ, pe ki nwọn ba wọn fi si iwaju awọn Aşoju-ilu mẹta,—Şingulu, Mọ ati Jonsi, Lọya Şingulu koi ti ku nigbana.

Awọn Ẹgbẹ Dẹmọ si yan ikọ mẹfa lati lọ ri Ijọba nipa rẹ.

Nigbati o di lọjọ 25 oşu *March* ọdun *1926*, Ọlọla Dokita Adeniyi-Jonse, Ọgbẹni Jackson, Lọya Zizer, Ọgbẹni Shackleford, Dokita Caulcrick ati Ọgbẹni Macaulay nwọn lọ ri Ọgbẹni Oyinbo Ruxton Igbakẹta-Gomina nwọn si fi ọran Itẹ-oku na si iwaju rẹ pẹlu ọrọ omiran ti nwọn tun ba lọ lọjọ na, Igbakẹta-Gomina si fun wọn ni esi nigbana pe bi Ijọba ba ti ri si awọn yio jẹ ki—ilu mọ.

Lẹhinna ni awọn Ẹgbẹ Dẹmọ tun gbọ wipe awọn Jamat tun da lọ ri Ijọba fun 'rawọn, eyiti ko jẹ ki ọran Itẹ-oku na le lori sibikan di ojọ arọ yi.

Ju gbogbo rẹ lọ, yio dara bi awọn Alaşẹ-Ijọba ba le ba awọn Imale ri si Itẹ-oku na.

A ti sọrọ pupọ ni peroporo igbati awọn paşẹ fun wọn pe nwọn ko gbọdọ sinku si Eko mọ, pe ki Ijọba jẹ ki awọn Alabojuto-ilu yọnda fun wọn ki nwọn ma sinku lọ ni Eko letoleto, nitoripe inawo ti nwọn nşe nipa gbigbe oku lọ sin ni Atan pọ pupọ, a si sọ irufẹ inawo ti o mu dani—şugbọn nigbati ẹnu gbogbo wọn ko şọkan ko jẹ ki awọn Ijọba le mọ ohun ti nwọn le şe nipa rẹ. Gẹgẹbi nwọn ti tun nfẹ dide nisisiyi pe wahala pọ nidi rẹ, o di igba na ki a to le mọ ohun ti a le sọ si.

Şugbọn o yẹ wipe ki ẹnu gbogbo nyin şọkan daradara, Jamat ti ko ba si fẹ ba ilu şe kokari pọ, o kuku dara ki o ma woran.

Emi ni ti nyin nitotọ,

KEKERE-AWO.

---

ORI III.

## IWA—ẸGBẸ KIKO ATI APẸRẸ.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*).

APA KẸFA.

Gbogbo igbesi aiye ologbe Dr. Marshall Hall fi han gbangba agbara ti iwa ni, ni kikọ ni ni iwa. Ọpọlọpọ awọn ẹni nla ti o şi wa lori ilẹ mọ pe ọna ti nwọn gba di nkan laiye jẹ nipa pe o la wọn ni oye. o si ran wọn lọwọ, bi ko ba şe bẹ ni ọpọlọpọ ọna ẹkọ ti nwọn kọ ati işẹ wiwadi ọna miran ti nwọn şe boya ni nwọn le şe awọn işẹ wọnyi ni asiko igbana. On a ma sọ fun awọn ọdọmọkọnrin bayi pe "Mu ẹkọ pataki kan kọ, ki o si kọ daradara, iwọ ko ni şai mọ" Ni ọpọlọpọ igba ni a ma la ọdọ ti o nrin mọ ni oye ọna titun, a wipe "mo fi eyi ta ọ ni ọrẹ, ti o ba mura si ti o ba kọ daradara, ọla nbẹ nibẹ."

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---

## NIJỌWO NI ENIA DUDU YIO BỌ NINU IWA-KIWA?

[ LATI ọWỌ ỌMỌ AWO ]

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Ko dede ti a fi lo ọrọ oke Iwe yi, mo rope bi enia dudu kan ba şe rere, gbogbo enia dudu gba lo ma fi yin, bi enia dudu kan ba si wa ninu ipo nla kan fun ire enia dudu gbogbo ni, şugbọn ohun kan lo wa ndun ni ninu rẹ pe, bi enia dudu kan ba wa ninu ipo nla, awa ara wa na la ma nşe Oluwarẹ ki işẹ tabi ipo na ba fi le bọ lọwọ rẹ, ohun pataki ti o dun ni ninu rẹ ni pe, awa enia dudu papa a ko mọ işẹ wa nişẹ, a ko si ntọju işẹ wa bi o tọ.

Aşerege ti ba ẹlomiran jẹ to bẹ ti ẹlomiran fi di ẹni ẹtẹ, ẹni yẹyẹ nipa iwa bẹ, o si jẹ ohun ti o buru ju larin awa ọdọ pe a ko mọ kọ-tọ a nfẹ lati la ọla ojo, a si fẹran lati ma jẹ nkan lajẹ pa bi o ba jẹ bẹ ni awọn oyinbo ti o ni işẹ tabi owo njẹ ajẹpa, mi o ro pe, nwon le lala lati wa la awa loju ni iha hin ki wọn si ko wa lẹkọ, eyi ti o jẹ pe a fi nşe ọmọ enia nisisiyi, ohun ti o mu wa sọ ọrọ wọnyi ni pe, oniye igba ti o jẹ pe, awọn ti o gba Ina mọnamọna (*Eletric Light*) ni opopo Ita Akanni, ma nwa Ina ti bẹni a ko ro pe ojojumọ ni Ina fi nbajẹ, bi o ba jẹ pe, wọn fẹ ma dan awọn Ina wọnyi wo bo dara tabi ko dara mo ro pe o ọsan (*day light*) wa fun iru nkan bẹ, ewo ni ki enia ma wa Ina ti lati tan ko ma ri ti o si jẹ pe on san owo fun Ina na loşoşu, a si tun şakiyesi pe iru nkan bayi ki nşẹ a fi igbati enia kan bẹ fẹ şe nkan pataki ni wọn ma nfẹ ina ku, o di pe ki ọkọ Iyawo Elere, na ma sare kiri, bawo ni Elere şe le mọ pe nwọn a pana mọ on loju nigbati ere ba ti kara tan, ki o ma wa Ina silẹ ati bawo ni enia ma tiraka tan ti o ma gba Ina mọnimọnamọna sile tan fun igbadun ara rẹ. ki o tun ma şe orunkun şoşoro a ti tan nigba ti ikan pataki bade lati ninu ile na, eyi ku dẹ a to Nitori a ti nsọ bayi oye ẹni oye ani fa gunlọmọ a si tun sọ pe iru nkan ba wọnyi kinşẹlẹ ni opopo ti awọn oyinbo

gbe wa. O ha jẹ pe ti wọn ko nbajẹ ní nda o, ilara ni ko jẹ, o mu mi ranti ọpọlọpẹ igba ti o jẹ pe nwọn npana mọ ni loju ni ibi ere pataki ni Glover Hall, ti o ba si di ẹrẹ daradara, a si wa ri pe awọn ọmọ eriwo fẹ jo ni ; iru iwa kiwa wọnyi ṣẹ lẹkan ṣoṣo nigbati awọn oyinbo njo ṣugbọn lati igbana a ko ri iru rẹ mọ ṣugbon bi o ṣe awa enia dudu la ma jo ni Glover Hall ni, bi a ba ti ṣe ana ojọ na silẹ ina ko ni tan ni ọjọ na iyẹn tabi ti wọn pana mọ wọn loju nigbati ere ba kara tan eyi ha dara larin enia dudu, ẹ jẹ ki awa ran ara wa lọwọ ki a si ma wa alafia ara wa ki inu wa si ma dun si ohun ti enia dudu ba ṣe ẹ jọwọ a bẹ nyin ọna ti a fi nṣe ina ti awọn oyinbo ti ko nfi nyọ wọn lẹnu eṣe e gẹgẹ fun awon enia dudu nitoripe ẹjẹ nyin ni wọn ṣe, ẹ fẹ so jaye, ki ẹ ba le jẹ ajẹpẹ rẹ, iwa idani lara ẹ mu kuro lọna, nitoripe enia ni lati gbadun ohun ti on san owo fun, ti o jẹ pe o kan ogun ki o to ri owo na, ba wo ni ẹ rope yio ti ri fun enia, ko ṣe wahala lati ṣe nkan na tan, ko wa jẹ pe ko ni ma gbadun rẹ nigbakugba ẹ jọwọ ẹ fi gbogbo osan ṣiṣẹ, ki awọn ẹrọ Ina mọnamọna (*Electric Light*) le gbadun ma won lalẹ, od' ọwọ nyin o, bo ṣere, ō ba.

Emi ni tiyin nitotọ,
ỌMỌ AWO.

---

## KA FI ỌRỌ RO ARA ẸNI WO.

Igbe aiye enia kun fun orişirişi iyipada ati ewu, eyi ti o ma de ba enia lẹ kọkan gẹgẹ bi idanwo, omiran a de ba enia lati fihan pe igbẹkẹle enia asan ni. Nitoripe boya o ti gbẹkẹle ẹnikan gẹgẹ bi ọmọ iya tabi ọrẹ pataki tabi ẹbi pe hawu ! nigbati lagbaja ba si wa ko si ewu, nigbati aiye ba si wa lọwọ rẹ tabi niwon igbati o ba ti nri jẹ ti ori mu ti ọmọ ara aiye nba o jẹ ti won ba ọmu, o ko le mọ iru ipo ti o wa, o di igbati adanwo aiye ba de si o to mọ ipo ti o wa. Owe awọn baba wa kan lo sọ bayi pe, ajojẹ ko dun bi ẹnikan ko ba ni, bi a ba ni la ṣajọjẹ. Ẹgb n miran wa ti o jẹ pe yio ma fẹ ọ niwon igbati o ba ti ri jẹ ti o si ri mu, ọrẹ miran wa ti yio fẹ ọ pẹlu ohun gbogbo ti o ni yala nina riri jẹ ni tabi ninu airi jẹ ninu kikẹdun ninu ironu, iponju ati wahala aiye eyi ti o jẹ pe kosi ẹda ti o le wipe ayipada aiye ko le de ba on, nigbati oluwarẹ ko gun igi ko ri ẹhin aiye Ọlọrun ko fi han ẹnikan bi ẹhin ọla yio ti ri.

Nitorina ẹnikan ti o nfẹ iranlọwọ sugbọn iwọ ti o jẹ ọrẹ rẹ tabi alabagbe tabi aladugbo ti o jẹ pe gbogbo ohun ti a wi wọnyi lo wa ni arọwọto tirẹ ṣugbọn iwọ ko lẹ ṣe fun aladugbo rẹ, lotọ ni ẹlomiran wa ti o jẹ pe o nfẹ iranlọwọ ṣugbọn iwọ rẹ ko jẹ ki ẹnikẹni le doju kọ lati ṣe iranlọwọ na fun ṣugbọn ẹgbọ bi Bibeli ti wi pe ẹuiti o ba mọ rere ṣe ti ko ṣe, ẹṣẹ ni fun anu la ba gbaiye. O ṣokunkun loju wa nisisiyi, ṣugbọn Ọlọrun Olodumare ẹniti gbogbo nkan ṣipaya fun ko ṣanu fun gbogbo wa o. Olowo nyọ talaka si nyọ pẹlu. Ọlọrun ṣe ohun gbogbo meremere, olukuluku ohun gbogbo si ni akoko tirẹ. Igba ẹrun nbẹ bẹni igba ojo igba orun ati igba oṣupa, igba gbigbin, ati igba didagba ati igba kika ohun ti a gbin ti Ọlọrun ti ṣe gbogbo igba ni akoko ti wọn bẹni o ṣe orişirişi adanwo bẹni igba kikun nbẹ ati igba rirẹrin ṣugbọn bo ti wu ki enia lowo to yio ku, bo si ti wu ki enia talaka to yio ku, ṣugbọn olukuluku gbogbo wa ni yio jihin tirẹ ni ojọ Idajọ, bi o ba ṣe rere fun ọmọ ẹnikeji rẹ iwọ yio ri bi bẹ kọ, Ọlọrun mọ ohun gbogbo, nitoripe Ọlọrun nikan ṣoṣo ni ohun gbogbo ki wọn ki ṣe alaini ko si gbagbe ẹnikan ninu awa ẹda rẹ afi ẹni to ba tan ararẹ oluwarẹ ni Odumare atan ṣugbọn Ọlọrun ki ṣe ibi nitorina ẹjẹ ki afi ọrọ ro ara wa wo, mo duro nihin.

Emi niti nyin,
RIRO NITI ENIA ỌLỌRUN LOLUṢE

---


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jọ oju lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ

Orişi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

## EKO AKETE

EKO, SATURDAY, APRIL 28, 1928.

### AT' AWUN ATI 'GBIN L'ẸRU ỌSANYIN O!!!

Ni ọjọ tabi ni igba lailai ni Gẹsi ti sofin ẹru tita larin gbogbo Enia Dudu, ti nwọn si ṣi ọna òwò; awọn baba baba wa ati awọn enia akoko yi lo gbadun bi aiye ti lọ si lakoko na: itura, alafia ati irọra wa fun t'onile t'alejo ni ilẹ yi, fun ọpọlọpọ odun ni gbogbo nkan nlọ dede ni igboro ilẹ yi tobẹ ti o fi jẹ owe fun awọn kan nigbakugba ti awọn ara oke ba fẹ wa ṣiṣẹ nilẹ yi pe "owo mbẹ l'ẹsẹ odo."

Ṣuṣa enia ninu awọn ara wa lo le la ala pe akoko kan mbọ ti gbogbo idẹra ati itura yi yio rekoja, yio si di nkan itan, ṣugbọn bẹ lo ri lode ti oni. Ti a ba si fẹ bi ara wa lere pe kilo mu ssababi yi wa? Esi ti a le fi ni pe inira ti o farahan l'Eko loni ti bẹrẹ diẹdiẹ lati igbati Gomina Egerton ti da ilu Eko pọ mọ ilu awọn Kuẹkuẹ; ile miran ti onile tilẹ nbẹ awọn enia ki nwọn ma ba on gbe ile, ko ha ti di hihaya ni owo geregere ni ọjọ oni bi? Ki iṣe eyi nikan; inira yi si tubọ pọ nigbati awọn enia nya wa si Eko lati awọn ilu miran: ekun kaka ni ẹlomiran fi le ri ile haya; irufe nkan bayi pọ tobẹ gẹ ti o jẹ pe awọn ẹlomiran ki b'eni b'eji ki nwọn tola ile wọn gbẹrẹgẹdẹ si ọna meji fun fifi haya, ti nwọn si nhamọ alawẹ kan to ku, ilu nfun lojojumọ, ko si jẹ ohun ti o ya ni lẹnu lati ri pe ọgọrọ ṣabu lo di sisun fun awọn alejo eyiti awọn onile ti fi haya fun wọn. Ẹ tun gba ọkan si; o ti di ẹmelo ni awọn kan jẹ kumoyo ti nwọn si ṣigbo kuro ni ilẹ yi lo gbe ilu bi Saro: ani sẹ o di Lọya tabi Dokiṭa tabi Wọnlẹwọnlẹ melo ti nwọn ngbe Eko lo ti lo ṣiṣẹ ni ilu bi Saro tabi ilu Aganyin ti nwọn si fi ọhun ṣe ile? Inira Eko yi tubọ pọ si nigbati Reluwe fọ gbogbo ilu Hausa nigbati Gomina Lugard tun fi da Eko ati ilu Kuẹkuẹ pọ mọ ilu Hausa; nigbati awọn Gomina wọnyi ṣe irufẹ didapọ bayi, pupọ enia ati awọn onişowo ilẹ yi dun ni ko mọ o ha jẹ pe awọn ara wa wọnyi ti a sọ pe irufẹ idapọ ilu pọ bayi ko dunmọ korira awọn ilu wọnyi ni? Agbẹdọ, ohun ti awọn ara wa igbana fi oju sun ni pe irufẹ idapọ bẹ ko le ṣai mu ibajẹ ati fifọ òwò (trade) wa: ṣugbọn gẹgẹbi ati jẹ "ẹru" Ọsanyin eyini ni Oyinbo, ẹnu Enia Dudu kọkan ko to 'lẹ lati sọ okodoro ọrọ otitọ yi fun awọn Gomina igbana. Ki a so ni gasikiya, a tanma pe awọn Oyinbo Onişowo nikan ni irufẹ dida ilu pọ bayi gbe ṣtun nitori nwọn ri owo tamutamu lati fi ṣe òwò, nwọn ko si jẹ anikan dajẹ bi ọpọlọpọ ninu awọn onişowo Enia Dudu.

Ninu hilahilo yi si tun ni Ijọba Gomina Thomson di ẹru owo "olori jori" ru ilu, ti o jẹ pe o sọ ilu Eko ati agbegbe rẹ di ẹru ati irandiran, a le ke gẹgẹbi a ti nke lati ọjọ jojo wa, ṣugbọn ko si idẹkun ofin na, bẹ Ijọba Gẹsi ki nwọn fi oju anu wọn wo gbogbo Eko ati ilu agbegbe rẹ ti nwọn le fẹ gba owo yi lọwọ wọn.

Ohun ti Eko ko iẹ ko yẹ ki o ri ni igbọnsẹ—Ilu l'Are ngbe o!!

### ATARÈDÈ ATARÉDÉ KA GBỌ TI JESU RE MO MỌ.

APA KEJI.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU. ]

Mo bẹrẹ f'oji,

Nigbati ọrọ ba di kara-n-gida bayi, kini Afa Ṣọṣi ti o gbe iyawo fun wọn le ṣe; iṣẹ di iṣẹ Lọya ọrọ di ti Kotu; Onidajọ Kotu nikan ni o le fun won ni Iwe-Ikọsile, bẹni Afa ti wipe, "Awọn enit Ọlọrun ba ti so ṣ'ọkan, ki ẹnikẹni maṣe ya wọn." Ati li ainani ikilọ ati ofin Testament titun wipe, "Ẹnikẹni ti o ba gbe obinrin ti a kọ silẹ ni iyawo, o ṣe panṣaga," igba pupọ ha kọ ni ẹnikan tun ngbe obinrin ti ẹnikeji rẹ kọ silẹ ni iyawo gẹgẹ bi ofin Ilu Gẹsi ti o l'odi si ti Bibeli ti Ṣọṣi si nfun awọn mejeji ni Sacrament tabi Onjẹ-alẹ Oluwa jẹ lẹhin na.

Eyi tun jẹri si ọrọ ti a sọ siwaju pe nibikibi ti ofin tabi aṣa ilu Oyinbo ba yatọ si ti Bibeli, ti ilu wọn ni nwọn ntẹle, ati pe nitorina, arede ti a ngbe, aṣa ilu Oyinbo ni, ko nṣe igbeyawo ti Onigbagbọ.

Ju bẹ lo, lakoko kan ri, o lodi patapata si ofin Oyinbo fun ara ilu Jew lati gbe Onigbagbọ tabi Christian ni iyawo, ẹniti o ba si ru ofin na, ina ẹbẹ ni nwọn nda sun nwọn laye, titi nwon a fi jona di eru patapata, bẹ gẹgẹ si ni ara England ko gbọdọ gbe ara ilu Wales ni iyawo. Ofin yenyi ti yipada diẹ nisisiyi, ṣugbọn, sibẹsibẹ titi di oni oloni, ọmọ ọba ilu Gẹsi to ba gbe obinrin to nsin ẹsin "Aguda" (Roman Catholic) ni iyawo ṣẹ si ofin ilu, ko si le jọba bi oye ọba tilẹ kan a, ngbati baba rẹ ba wọ aja.

Bi Oyinbo German kan gbe obinrin Oyinbo Gẹsi ni iyawo ni ilu Gẹsi bi England tabi nomiran, ayaṣebi nwon ba ṣe isin igbeyawo na ni ilu Gẹsi gẹgẹ bi nwọn ti nṣe gan ni Germany, bi bẹkọ, ijọkijọ ti ọkunrin German ọko iyawo Gẹsi yi ba de Germany ilu rẹ, ko si ofin kofin to le di i lọwọ lati gbe iyawo miran lai kọ obinrin ti o ti gbe ni iyawo ni ilu Gẹsi silẹ.

Bi oyinbo Gẹsi onigbagbọ ọkunrin si gbe onigbagbọ obinrin Faranse ni iyawo ni ilu Faranse, igbeyawo na ko murọ mọ bi nwọn ba de ilu Gẹsi, ayaṣebi a ṣe eto igbeyawo na gẹgẹ bi ti Gẹsi ilu ọkọ bi o ti lẹ ti jẹ pe obinrin Faranse ni a gbe ni iyawo ni ilu Franse.

Ko yẹ ki eyi ri bẹ rara, ti o ba ṣe pe igbeyawo onigbagbọ lasan ni, laisi ọrọ ofin tabi aṣa ilu nibẹ. Ni ilẹ yi, onigbagbọ ọmọ Eko le gbe onigbagbọ obinrin Adelamu ni iyawo, Ijẹbu le gbe Ijẹṣa, ara Ogbomọṣọ le gbe Tapa, Ẹgba le gbe Iṣẹkiri, ara Ibadan le gbe Hausa ni iyawo, Isobo le gbe obinrin Oyinbo Gẹsi papa ni iyawo. Ko ṣe pe nitori gbogbo wọn jẹ onigbagbọ ni eyi fi le ri bẹ, bikoṣe pe gbogbo wọn lo wa labẹ aṣa ati abo Ijọba Gẹsi. Ngbati a ndi pali Collar mo ọrun pẹlu akisa Tie bi ologbo, ti a nwọ ṣokoto fatofato, ti bata yo koko Corn si wa l'ẹsẹ, Oyinbo ha kọ ni a nfi ara we?

Gẹgẹ bi aṣa igbeyawo ilu Gẹsi yi, t'ọkọ t'aya le gbe iyawo ni Kotu lai tilẹ de Ṣọṣi rara, akọwe Kotu Registrar to ma gbe e fun wọn si le jẹ Imale tabi Keferi. Iya fẹ, iya kọ, Baba fẹ, baba kọ, ko di oyinbo lọwọ rara lati gbe iyawo, iwa ẹdaju buruku ti Oyinbo ko wọ ilu wa to si nje opọlọpọ awọn ọmọ wa ni 'ya nile ọkọ nisisiyi.

Gẹrẹ ti Oyinbo ba ti gbe iyawo tan, ko mọ iya tabi baba mọ, afi on pẹlu aya rẹ nikanṣoṣo, ti Ọlọrun ba si jaja yoda ọmọ kan tabi meji fun wọn, ofin ilu wọn ko tun bikita fun iya tabi baba awọn mejeji mọ.

A ngbọ Famili, Famili family, ọkọ aya ati ọmọ nikan ni ofin Oyinbo mọ ti nwon si npe ni "Family." Baba ko si ninu family, ti wọn, iya ko si nibe; ko si ẹgbọn, ko si aburo. Eyi lo jẹ ki ọkọ nikan le jẹ ogun gbogbo ohun ini aya tefetefe, ki aya si le jẹ ti ọkọ, ẹnikẹni ninu awọn mejeji iba fi akuṣẹ arugbo iya tabi baba silẹ l'aiye, ka ma ṣẹṣẹ sọ ti aburo tabi ẹbi miran. A ha le ka iye ijẹkuje ogun ologun bayi ti awọn alarede Enia Dudu papa ti je ni Eko yi gẹgẹ bi ofin Oyinbo, to ba si jẹ pe ofin Bibeli ni eyi, ki awọn Afa jẹ ki a gbọ.

Nipa ọrọ arede yi, aṣa tabi adiẹ olopipi to jo Oyinbo lọ ko si; bi ọkọ ko pe aya ni orun fun ijọ melo kan, eyiti itiju ko njẹ ki awon obinrin wa le ro iru ẹjọ bayi si ita fun eti meji gbo, ẹjọ ni Oyinbo yio pe ọkọ rẹ si Kotu ti yio si haya Lọya ti ndi, ti yio si sọ fun onidajọ nigbangba Kotu loju gbogbo enia pe oko on ko fi ọwọ kan on lati ijọ mẹta wa. Onidajọ yio si paṣẹ pe ki ọkọ bẹrẹsi lọ sun ti aya rẹ, ko si san owo irin ẹsẹ. Bi ọkọ ba tun kọ lati sunmọ iyawo rẹ lẹhin aṣẹ yi, bi Kotu ba fẹ o le jẹ ẹ ni iya fun "Contempt of Court" tabi iwa ẹgan si Kotu, bi ori rẹ ba si ta ko o, Onidajọ le fi si ẹwọn nitoripe ko sun mọ iyawo rẹ.

Bi o si ṣe aya ni ko fi aye silẹ fun ọkọ, bẹ gẹgẹ ni okọ yio pe e lẹjo, bi onidajọ ba si fi aṣẹ si i, ti nwọn ba pada de ile, ti obinrin ko sibẹsibẹ, to si sọ fun ọkọ rẹ gbangba po on ti ri Baba Isalẹ to ntẹ on ni bifin ni bokẹlẹ, to si ntẹ on lọrun nigbakugba, ohun ti ọkọ le ṣe ni pe ki o pe aya rẹ l'ẹjọ ikosilẹ ati gẹgẹ bi ofin arede Gẹsi yi ti nwon npe fun wa ni iyawo onigbagbọ, ọkọ lo ni lati haya Loya fun 'ra rẹ, ki o si tun fi owo apo rẹ haya Loya fun obinrin, o si ni iye owo tiantian ti ọkọ ni lati san ni asantẹlẹ si Kotu, ninu eyiti aya rẹ yio ma fi jẹun, fi da 'ṣọ ati lilo fun ohunkohun to ba fẹ titi ẹjọ yio fi pari, nwọn si le ro ẹjọ na siwaju, sẹhin, ki ọkọ tun jẹbi le e lori, papa to ba jẹ ọkọ to ni ẹrẹ obinrin miran s'ode laṣiri. Irufẹ ofin bayi lo je ki ọpọlọpọ pauṣaga alarede aya miran nilẹ yi di egungun ẹja ha bale wọn lorun— iru ofin bayi lo jẹ ki "Best man" tabi igbakeji ọkọ iyawo tun le pada di ọkọ obinrin ti o ṣe Best man fun ọkọ rẹ nijọ iyawo, ti obinrin na nbimọ fun u, ṣugbọn ti ẹjọ ọko ko wọ Kotu nitoripe on papa ni ọmọ l'ode. Bi oko titẹ bi ọmọ sode, iyen lo ha wipe "Best man" le jẹ iyawo rẹ ni ajẹgun ti oriṣa njẹ igbin? Ani, iru ofin arede Oyinbo yi lo jẹ ki opọlọpọ onigbagbọ di agabagebe nitori ati ri aye jẹ Sacrament tabi Onjẹ-alẹ Oluwa ni Ṣọṣi, ti ẹlomiran ninu wọn, ninu agabagebe rẹ ṣe abosi titi o fi sin ọmọ rẹ obinrin ni iyawo fun ọko ni adugbo kẹdọgbọn lai sọ ohunkohun fun "my dear" rẹ to wa nilẹ.

Gẹgẹ bi ofin arede Oyinbo, oko le kọ silẹ nitori agbere. ṣugbọn aya ko le ko ọkọ silẹ nitori agbere nikanṣoṣo, ṣugbọn o ṣoro fun ọkọ ti iyawo rẹ wa ni Olowogbowọ, ti ale rẹ wa ni ita Balogun, tabi eyiti o bi ọmọ sode lati kọ alarede rẹ silẹ bi iyawo na tilẹ nhu iwakiwa, bi nwọn ba si pe ara wọn lẹjọ, eyiti Kotu le ṣe ni pe ko fun wọn ni iwe ipinya ti a npe ni "Judicial Separation,"

lẹhinna, olukuluku wọn le ma lo ni ọtọtọ, ọkọ yio ma san owo ti a npe ni Alimony fun iyawo rẹ loṣoṣu, oṣu to ba se, Kotu le ta ẹru ọkọ na ni gbanjo, tabi ko gbe on papa ju si ẹwọn 'gbese.

Nwọn le wa ni ọtọtọ bayi fun ogun odun lai sun mọ ara wọn, ṣugbọn pẹlu gbogbo ipinya na, bi ẹnikan ninu wọn ṣeṣi lo gbe ẹlomiran niyawo, o gbe Jombo—ẹwọn idi rẹ yio gun de Saro fun ẹṣẹ ti a npe ni "bigamy."

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## ỌRỌ GARI YI TI JẸ KẸ?

Si Oniwe-irohin *Eko Akete*,

O jẹ ohun ti a ma nṣe afiyesi wipe bi awọn Imale ba ti ṣe odun wọn buṣe ni Gari (*Farina*) ma nṣọwọn ni ilu.

Mo bere lọwọ awọn ero ọja kan pe ki lo ma nmu bẹ wa, oluwarẹ so fun mi pe nitotọ bi awọn Imale ba ṣe ọdun, awọn Ijẹbu ati ara Ẹpẹ to nmu Gari wa si ọja Ejinrin, ki iko gari wa si ọja tobẹ laseko ọdun bayi, nitori lẹhin ti gbogbo aiye ba ti ṣe ọdun buṣe ni awọn Ijẹbu ṣẹṣẹ ma bẹrẹ ọdun ni ṣiṣẹ: gari ti awọn ara Ẹpẹ si le mu wa ko le to ta fun ero ni ọja.

Nigba miran awọn Ijẹbu ma nfi odindi oṣu kan abo ṣe ọdun, awọn miran ninu wọn si le ṣe ọdun yi titi ọdun Ileya fi ma de, nipa bayi nwọn nfi odindi oṣu bi mẹta gbako ṣe ọdun, nipa eyi ni Gari fi nwọn, awọn Ijẹbu ti o ba le tiraka rin gari diẹ, iwọnyi ni nwọn ko wa ta ni ọja.

Ati pẹlu iba gari diẹ na ti awọn ero ọja ba nri mu bọ wa si ile, gẹgẹbi o ti jẹ pe ki iṣe ilu Eko yi nikan ni nwọn nwọn nda gari duro si, sibẹsibẹ, nwon ko ni ṣe alai tun ko wọn ranṣẹ si awọn ilu Oke ati Oke Okun fun tita, eyi yi lo jẹki gari ma nwọn.

Nibiti ọran na gbe ṣẹpa si ni wipe iba jẹ wipe bi gari ba wọn bayi, awọn onișowo gari yi nda gari duro si arin ilẹ yi nikan fun aseko diẹ ti gari yio tun fi yọ ju daradara, iba dara julọ lọju temi a ko le so wipe ki a ma ṣe fi gari ṣowo lọ si idalẹ, ṣugbọn nwọn ni ti ara ẹni ni a nkọ gban in ki a to gban agbanniregun to! to! o, ti ilu wa ni a ba kọkọ toju na, ki a to toju ilu onilu.

A ko sọ wipe ki a ma ṣe mu gari ranṣẹ ṣọwọ si idalẹ arara, nitori opọlọpọ enia lo ni enia ni idalẹ, ti a ni lati ma fi gari ṣowo si fun jije, ni pataki o yẹ ki a jẹ ki ilu ma wa ni itẹlọrun onjẹ kan na ki a to ma fi ṣowo ranṣẹ si idalẹ, bi onjẹ kan tilẹ pọ ni ilu, ẹniti o ba fẹ o le mu tirẹ ṣowo lọ si ilu Oyinbo a donkiya, iyẹn ko kan ẹnikẹni rara.

Ohun ti o si nmu ẹlomiran mu onjẹ ṣowo lọ si idalẹ ni aseko ti o ba wọn bayi ni ere ajẹju, ejiti a o ba fi ta a ni ilu ẹni papa, a o ma sọ wipe ko to pe fun ni, bikoṣe ki nwọn fi ṣowo lọ si idalẹ nipa ero bayi, ọpọlọpọ enia ti padanu lori ọja rẹ, bi ẹlomiran di gari ti o ni on fẹ fi ranṣẹ si idalẹ ki gari na to de, o le bajẹ, tabi o le wọ omi ninu ọkọ adanu de eyiti a o ba fi da wọn duro ni ilu ki a ta kuro, bi toro ni oluwarẹ ri lori rẹ ni kobo si ti ki o gba kadara iro ni bi ko di igba ti a ba ti ọrun bọ gbese, nigbana ni ẹlomiran yio to tẹ ẹ lọrun.

Ko si ẹniti ko mọ bi iṣẹ ti ṣọwọn si laseko yi, debi ti enia ma fi owo ọwọn jẹ ọja ọwọn.

Ọpọlọpọ enia lo wa ti o ni ọmọ lọdọ ti o ntọju, bi o ti wu ki o ri o ni lati fun wọn ni onjẹ ko si si onjẹ miran to le tẹ ọpọlọpọ ara ilẹ yi lorun lẹhin gari, bi ẹlomiran ti ni ọmọ pupọ lọdọ, bẹ ni okunrin ni aya meji-mẹta lọwọ tulasi gari yi ni onjẹ fun wa.

A ko si ni ilu Saro tabi ni ilu Tapa, debi ti a le ma fi ojojumọ jẹ iresi bi ẹiyẹ ati pẹlu ni iwọn igbati oluwarẹ ki iṣe oyinbo, oyinbo miran ti o ti pẹ ni ilẹ yi, o fẹrẹ le daba lati ma jẹ ọka-gari, bi a tilẹ ni a le ma ṣe amolumala onjẹ, nibo ni iwọnyi gbe le tẹ ni lọrun de?

A bẹ ẹnyin Ijọba ki ẹ jọwọ ki ẹ ba ni fi oju agba si ọran na, nipa awọn ẹniti nko gari ṣowo ṣọwọ si idalẹ, a ko ni ki nwọn maṣe ṣowo gari, ṣugbọn laseko ti gari tabi onjẹ miran ba ṣọwọ ni ilu ko yẹ ki a tun ma ko won ranṣẹ si ilu miran— ẹ maṣe jẹ ki a fi ọwọ arawa fa iyan wọ ilu, nitori a ko le sọ wipe ki awọn ẹniti o nrin gari maṣe ṣe odun wọn.

ỌMỌ ILU.

---

## OLUSAKIN'S COLUMN.

### "Unity, Liberty Charity."

The Fourth Annual Thanksgiving Service of the Friendly Societies' Conference, consisting of Foresters, Odd Fellows and Shepherds was held at St. Paul's Church, Breadfruit, Lagos, on Sunday, the 22nd April, 1928, at 4 p.m. The Venerable Archdeacon E. A. J. Ogunbiyi, L.Th., preached a well deserving sermon

Text.—Acts of Apostles, Chapter vii, verse 26. The collection which was in aid of St. Paul's Mutual Aid Fund amounted to something like £6. We congratulate Mr. H. S. A. Thomas, the General Secretary, and all concerned for the success of the functions.

### Bill to Change Marriage Laws.

LEGALISING UNION WITH DEAD HUSBAND'S NEPHEW.
MANY HARDSHIPS.

*Views on Sir A. Shirley Benn's proposals—Child Sufferers.*

Sir Arthur Shirley Benn, M.P., yesterday explained his reasons for proposing to ask permission in the House of Commons on Monday to introduce a Bill to Legalise

The union of a woman with her nephew by marriage, and that of a man with his niece by marriage.

A Bill with this object in view was introduced last year, and got through Committee, but was not proceeded with owing to lack of time. "Such a Bill," said Sir Arthur, "would relieve many people who suffer because of their present anomalous legal position. I have had between 100 and 200 letters from victims of the law, asking me to help them.

"The children of their at present illegal union are the worst sufferers.

"There are cases where a man has married his niece by marriage at an English Embassy or an English Church abroad many years ago. They have come to England thinking their union was legal, and they have discovered all sorts of legal disabilities.

PENSIONS BAN.

For instance, widows of soldiers cannot draw pensions because they married an uncle by marriage. There are extra taxes in such cases, yet these inheritances are really in the family."

The Bill, if it is passed, will remove a stigma from many worthy people," said Mr. C. G. Ammon, M.P.. "I know of no single religious objection."

Mrs Charles Harnibrook, a member of the Bishop of London's Morality Committee, expressing a personal opinion to *The Daily Mirror*, said she could see no reason whatever in withholding the right of marriage of nephews and nieces by marriage.

"I simply cannot understand the mentality of anyone who suggests that a man would be jealous of his nephew, or a woman of her niece," she said. "Of course, there is the age question, but that has really nothing whatever to do with it. I have a grandchild who has an aunt a month younger than herself!"

DOCTOR'S VIEW.

One of the leading West End Doctors declared that there was no reason to suppose that the children of such marriages would be of a lower standard than the children of people who were less closely related.

The Rev. Dinsdale T. Young (a former President of the Wesleyan Conference) said: "On strict religious grounds I don't think there can be any objection to such a Bill becoming law."

"The objection I have to make is on the ground of indelicacy. Such close unions might hardly be decent. But I see the force of the argument that hardship in many cases would be removed by the passing of such a Bill."—*The Daily Mirror.*

**Promotions.**

Mr. Moses Adekunle Beckley, 1st Class Clerk, Survey Department, Lagos, has been promoted to the rank of an Assistant Chief Clerk, as from the 1st April, 1928. Congrat. Also Mr. Othniel O. Taylor, 1st Class Clerk, Treasury Department, Lagos, earned a similar promotion. Well done.

## Abeokuta Notes.

[*By our correspondent*]

Abeokuta, April 17.

"Mr. Oladipo Ṣowande, President of the Ake Court, Grade "A" has resumed his duties after an absence of about eight weeks on leave. With his arrival the Court appears to have resumed the atmosphere distinctive of this high tribunal in Egbaland. During Mr. Ṣowande's absence an illiterate President was made to sit over cases in this important Court with a senior Judicial clerk to assist in taking notes of evidence. This arrangement appears to have given much cause for dissatisfaction and was generally regarded here as a retrograde step. It is the general opinion that illiterate chiefs sitting as Assessors with a Judge of repute may be an excellent arrangement but that it was quite another matter when one of these chiefs is appointed as the President without competent guide."—*The Nigerian Daily Times.*—

[Why is it that the next Judge in order of merit in the person of Mr. George I. Beckley, President Judge, Grade "B," Abeokuta, was not asked to relieve Mr Ṣowande, before placing an Illiterate President to sit over cases in such an impoatant Court?]

**Birth.**

Madam Adedoja, wife of Mr. W. Adedoyin, 1st Class Clerk, Traffic Audit Section, Nigerian Railway Ebute Metta, of a female child, on Sunday, the 22nd April, 1928. Both mother and child are reported to be doing well. A ba ọ yọ.

OLUṢAKIN.

## HA! KILO TO YI?

Niwọn agogo marun ọjọ Wednesday 25th oṣu yi ni ọdọmọdekunrin kan ti a npe ni George aburo Mr. Orunbus Cole ti ile iṣẹ P. & T. lọ ta ara rẹ lokiti lati ori igi mọngoro to wa ni ẹba ṣọṣi to wa ri gbangba ita awọn ọlọpa ni Ọbalende. Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn gbe lọ si ọgba alarun, ṣugbọn ki nwọn to de'bẹ ẹlẹmi tı gba. Kilo to yi?

Ki Olodumare alanu julọ ki o ma ṣọ wa lọwọ nkan bayi o.

## PRESS NOTICE.

His Excellency the Governor will invest ODIN TOM FAULKNER, Esq., Director of Agriculture, with the Badge of a Companion of the most Distinguished Order of Saint Michael and Saint George in the Council Chamber on Friday the 4th of May, 1928, at 9 30 a.m.

Uniform will be worn by those Officials who are entitled to wear it.

## To Lease.

A House at No. 151 Upper Street, Lagos.

Isọ ti o wa ni Oke-Arin jẹ *pound* kankan ni ọdọdun kiṣe oṣoṣu.

# Iyin Oluwa Medicine Store

## K. B. SAVAGE,

CHEMIST & DRUGGIST.

STOCK :—

## YARO

***The oldest and best Infants Preservative 1/6d & 3/-.***

## WIRELESS FEMALE PILLS

***The scientific preparation for all monthly Disorders peculiar to Females. 4/6d per bottle.***

## KADUNA BALM

(IPARA AWO'GBA ARUN).

***Can be applied in 100 different ways !!! 1/-.***

## Write or call at :—

88, Broad Street, Lagos,

6, Martins Street,

41, Alli Street, Faji Market,

109, Griffith Street, Ebute-Metta.

**Watch this space every week.**

W


Disinfectant Soap of
Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic Soap in your home—it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap
Tablets
MAGNET SOAP
MAGNET
MAGNET
SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH.

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### RẸMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painful and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati orișiriși arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
**Postage 2/6 extra.**

WHITE'S

## WONDR I L BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy of Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oșu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oṣun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

Who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address:*—"WHITE LAGOS"

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

## TO LET.

One Splendid Pleasure Car
No. L2754.
**Always at everybody's service at Tinubu Square.**
For Terms, Apply to:—
A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

# ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmin[illegible] ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju [illegible] Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aşetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi a[illegible] awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun [illegible]ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.

Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.